# Awọn Oloye Titun ti o ṣẹṣẹ jẹ ni Shomolu



## Ọmọ-Ọba Laoye lọ ṣe ibẹwo-awọn enia rẹ ni Ghana

EKO.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu ti o kọja yi ni Ọmọ-Ọba L. L. Laoye, ọkan ninu awọn aṣiwaju Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) kuro ni Eko o si de si ọdọ ọrẹ rẹ Ọgbẹni Gbadamosi Alagbe ni Nsawam ọrẹ rẹ na si gba a lalejo rekẹrekẹ, awọn enia pataki-pataki si wa ki i nibẹ, inu won si dun lati gbọ bi awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifere ti Oke Ọya ti wa ni isokan si. Lasisi Manija ati Alagba Ladoke si ṣe ni alejo pupo nibẹ.

Bena ni nwọn tun gba a lalejo ni Pramkese ni ọdọ Raji ati Raimi Aṣiyanbọla. Lẹhinna ni o kọja si Kumasi lọdọ iyawo rẹ Muniratu Ajoro ati Kudiratu ọmọ rẹ, ọpọlọpọ awọn gbajumọ ni o tun gba a lalejo nibẹ, o si tun kọja si Tarkwa lọdọ aburo rẹ Bello Ejilami, o si tun de ọdọ aburo rẹ Jimọ Laoye ni Dunkwa. Lẹhin ti o wa dagbere fun iyawo rẹ a' ọmọ rẹ ni Kumasi ni o ba kọja si Lome lọdọ Raji ati Adiyatu Ladunni.

Gbogbo awọn ọmọ Yoruba ti o si wa ni ilu Lome ni o gba lalejo lati ibẹ ni, si ti de si Eko ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu ti o kọja yi. Ni ọjọ keji o si ṣe ibẹwo Olotu "Irohin Yoruba" o si fun un ni irohin bi o ti gbadun irin-ajo rẹ na si, ki o to ma a kọja lọ si ibujoko iṣẹ-owo rẹ ni Jos.

## Ijamba mọto pa awọn enia meji

EKO.

NI alẹ ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadilogbọn oṣu ti o kọja yi ni ijamba moto kan pa oga alamojuto ile kikọ ti o ti nṣiṣẹ ni ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ti o si ti gba isimi lẹnu iṣẹ na.

Bi jamba na ti ṣẹlẹ ni nigbati mọto ayọkẹlẹ A7599 ti oga na wọ ati mọto akẹru kan LD9798 ṣeṣi kolu ara wọn ni Iddo ni oga na ba ṣẹṣẹ, o si ku ni ọjọ keji.

* * * *

Moto tun pa ọmọkunrin, ọmọ ọdun mọkanla ọmọ ile-iwe ni Apapa ni ọjọ Abamẹta ti ṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o kọja yi. Nigbati ọmọ na fẹ da Randle Avenue kọja ni mọto ayọkẹlẹ kan, LD4145 seeṣi pa a patapata.

* * * *

Ni ọjọ kanna ni ijamba mọto kan tun ṣe Ọgbẹni O. A. Majẹkodunmi, oga iṣẹ Ijọba ati aya rẹ ati awọn enia meji miran lẹṣẹ ni Clifford Street, Yaba, nigbati mọto ayọkẹlẹ wọn LB6542 ti nwọn wọ ṣojude lẹhin ti mọto na ati mọto LD3706 ti nwọn fi nko igi ikẹna ti seeṣi kolu ara wọn.



Laipẹ yi ni nwọn fiawọn enia mẹtalelogun jẹ Oye ni Shomolu lẹba Eko, Awọn Oloye tuntun na ṣe gudugudu meje, nwọn nawo-nara-nwọn si tun fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹ, yẹ ope ọjọ na lọrun. Aworan oke yi ni ti Oloye E.B. Ogunkọya, alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Mushin, nigbati o njo ilu gangan nibi oye na 2 Aworan keji ni ti gbogbo awọn ti o jẹ oye l'ọjọ


IRORA FẸRẸ JẸKI AWỌN APA KEJI NI IṢẸGUN!



1\. Iṣẹju marun pere ti o ku ki nwọn fun fere ikẹhin ni Joe seeṣi fi kokose ṣeṣe—o si ku bolu-agbawọle kan ti nwọn yio fi ṣẹgun!

2\. Joe dubulẹ si ilẹ, o nkẹ'rora. Lojiji, ọrẹ rẹ kan sare tọ ọ lọ. O ni "fi eyi pa a." o si gbe idẹ Mentholatum kan fun Joe.

3\. Lẹsẹkẹsẹ ti o ti fi Mentholatum atura ati adẹra pa a, Joe bẹrẹsi gbadun. O ku iṣẹju kan ki nwọn fun fere ikẹhin.

4\. Ah! Joe ti pada si aye awọn ti nwọn to si iwaju, o gba bolu ti nwọn gba si i si apakan lojiji—o si gba a wole! opẹlọpẹ iwosan Mentholatum, Joe ti gba ere-ije na la.

Bi o ba ni esanra tabi irora tabi ẹfori fi Mentholatum atura ati adẹra pa ibẹ. Lẹsẹkẹsẹ a ti mu riro na kuro nibẹ. Wa a si bẹrẹsi gbadun aiye. Mentholatum darajulọ fun jẹdijẹdi, pelu —a tete mu itura wa! Ri i daju pe, Men-tho-lay-tum gan an ni, ti o wa ninu awọn agolo ati idẹ bi irufẹ iwonyi ni ki o ra. Maṣe ra awọn odamodi!



Awọn ti o nṣe e nikan ni

MENTHOLATUM CO. LTD.

(Est. 1889) Slough, England

MENTHOLATUM

IPARA TI O DARAJU


## Adajọ sọ awọn mẹrin ti nwọn lu ọmọ Ẹgbẹ Afenifere sewọn oṣu mefa

IBADAN.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni Adajọ Agba Kotu Kekere kan ni Ibadan sọ awọn enia mẹrin, Macus Buraimọh ti apele orukọ rẹ njẹ "Scorpion Boy"; Laniyi Ajayi, Asifa ati Wahabi Arẹmu si ẹwọn oṣu mẹfa-mẹfa nigbati o ri i pe nwọn jẹbi ẹjọ t'awọn ọlọpa ba wọn ṣe pe, nwọn lu ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifere (Action Group) kan, Kansilọ J. Akinbọla, nwọn si dọgbẹ si i lara pupọ ni abule Ọgbagba lẹba Iwo ni ọjọ keji oṣu keji ọdun yi.

## Alhaj Oshishi ṣe ọjọbi

EKO.

LENULỌLỌYI ni Alfa -Alhaji T. K. Oshishi ṣe ọjọ-ibi ọdun kẹtadilọgota rẹ ni ile rẹ, Docemo Street. Eṣẹ awọn Alhaji ati Alhaja ati awọn gbajumọ ni o pe ṣọṣọ si ibi aṣeyẹ na.

Alhaji A. W. Jẹnmi ti o ṣe alaga sọ ọpọlọpọ ọrọ apọnle nipa ẹniti o ṣe ọjọbi rẹ na, bi o ti ṣe jẹ olufọkansin, onisuru, onilakaye, onimimọ, ọlọyaya ati ẹniti o fẹran tọmọde tagba tọkantọkan. Alhaji T. K. Oshishi si fi jijẹ ati "Fanta" ati "tango" tẹ gbogbo awọna alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun titi ilẹ fi ṣu.

Ajeijamọdun o.

## Ara ilu Urhobo kan pokunso

PORT HARCOURT.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu ti o kọja yi ni nwọn ri i pe Thompson Umoro, eni ogoji ọdun, ara ilu Urhobo ni Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o nṣiṣẹ alabojuto Ile-iṣẹ Shell-BP ti pokunso ninu ile-igbẹ ile rẹ ni Diobu, ibuso meji si Port Harcourt. Nwọn si ti gbe oku rẹ lọ si ilekulaku fun ayẹwo.

Nigbati Thompson Umoro siwo lẹnu iṣẹ rẹ wa si ile rẹ ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu ti o kọja yi ara rẹ le dada, nkankan ko ṣe e rara.

# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Mo ki nyin Olotu, ẹ ku ijo mẹta, o dun mi pe nko le wa a ri nyin ni ọsẹ ti o kọja. ohun ti o fa ni pe, o se mi bi aarẹ.

OLOTU—Emi paapa ro pe bi ko ba si idiwọ kan pataki, o ba wa ri mi gẹgẹ bi ileri ti o ṣe. Ṣe ara wa ya dada nisisiyi.

ALAPARA—Mo gbadun diẹ.

OLOTU—Kini o fẹ ri mi si ni ọsẹ yi?

ALAPARA—Mo kan fẹ ki ẹ mọ ibiti emi pẹlu arijẹnimadaru pari ọrọ wa si ni.

OLOTU—O dara ma a sọ o ki a gbọ o

ALAPARA—Nigbati mo bere pe ki o la mi loye diẹ bi nwọn ti nṣe ri onjẹ jẹ ninu Ẹgbẹ Oṣelu ti o wa, o kọ rẹrin arin-yikiti na, ki o to wa kan saara si Pẹnkẹlẹmẹsi lọna orun lohun

O ni Pẹnkẹlẹmẹsi ti n ọna onjẹ han awọn ki o to lọ si ọrun Alakeji aremabọ pe bomodeje- bagbaje k'iṣe ilẹ dida. O ni nipa fi fa awọn alaimọkan mora ki o si ma a ba wọn jẹ ki o si ma a ba wọn mu ki ẹ si jo ma a fi ọrọ jomitoro pẹlu wọn ni wa a fi ri wọn pajẹ.

O ni ṣe o mọ pe ti enia ba npurọ ti kọ rẹrin ti o ba si nṣawada ti o nrẹrin nṣe ni ọmọ araiye a ma a gba a tẹle e lẹhin, ṣugbọn ti o ba nsọ otitọ nwọn ko ni feti si ohun ti o ba nsọ nitori ọmọ araiye ko fẹ otito.

Mo tun bi i lere pe o ko ti sọ fun mi tara bi ẹ ti ṣe npurọ ri owo, boya ti o ba ṣeeṣe emi na a ma a pelu nyin, o ni "a nki i a nsa a, o ni o ko iti mọ ẹniti o ku, nwọn ni oni-igba ọkọ ẹlẹgba a-ada o tun bere pe ọkunrin tabi obirin, obirin a ma a roko? O ni mo nṣe alaye fun o bi irọ ti ṣe lere si, o tun mbi mi pe ki nsa la ọrọ molẹ pọn-nyan-un bi a ti ṣe nri owo, o fẹ gbe mi gbun Ijọba ni?"

Mo wa tun bi i lere pe Ẹgbẹ Oṣelu wo ni o rọ pe yio moke ninu idibo yi? O ni bi awọn olotitọ ko ba moke o daju pa awọn onirọ yio moke, ti awọn onirọ ba moke nibẹ ni awa gbe ri jẹ. bi o ba ri bẹ ẹ nṣe ni a o gba ilu ti a ma a jo kakiri pe:—

Aiye di ṣoki-ṣoki o sombolo
Aiye di ṣoki-ṣoki o sombolẹ.

Mo si tun bi i lere pe, kiniṣe ti inu nyin fi ma a dun si iwa aiṣootọ nigbati ẹ mọ pe ipalara ni yio jẹ fun gbogbo enia. O si da mi lohun pe "ti paari ọmọ ẹranko ko ba baje ti ọmọ enia ko ni i dun.

Mo tun wa bi i lere pe, nje ti awọn ẹgbẹ opurọ ti o gbẹkele ko ba fi moke nkọ? Kini o tun ku ti wa ṣe? O ni adaba ko ni naani a nkun igbe ni t'on ina njo eiyẹ nlọ. Bi ọran ba fi jẹ bẹ ẹ, ma a wa aye ti ma a 'i dapọ mọ awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre niyẹn, o ni gbogbo awọn ẹbi mi ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni nwọn, mo si tun ni ọpọlọpọ ọrẹ ninu wọn.

Mo si bi i lere pe, nigbati nwọn ti mọ o pẹlu awọn "jodi-jẹsọ" nwọn ko ni i gba o si Ẹgbẹ Olotitọ mọ. O ni iwọ ko ka itan ọmọ oninakuna ninu Bibeli ndan? Nigbati ọmọ oninakuna ronupiwada baba rẹ tun fi ayọ gba a pada, o tun pa ẹran abọpa fun un ti o fi ki i ku-abọ pe emi rẹ tun pada bọ wale lalafia.

Mo wa fi ye e pe toni ko jọ lana ni idibo ọtẹ yi nitoripe Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ta gbongbo yi gbogbo awọn ilu Naijiria, mo ni ṣe iwọ na ri i bi Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nfi moto ofurufu dara loju sanma, ati bi awọn olokoofurufu meji kan ti tun wa nyọmbẹ "AWO" ati Igi-Ọpẹ loju sanmọ, eyiti ẹnikan ko fi pitan ri pe iru re ti ṣẹlẹ ni Naijiria.

**Asa nfo fẹ ẹ**
**Awodi nfo fẹ ẹ**
**Rikiṣi ko j'adiẹ o fo fẹ ẹ**

Olotu o tun di igba kan na, Ẹ dibo f'Ọpẹ.

---


## ẸKUN-AGBARA
### egbogi aladun
**da ikọ rẹ duro**
**ki o si f'alafia f'agbara rẹ**



Fun iwosan iko ... alafia ati f'alafia fun ... agbari rẹ, mu Sante Pastille. Awọn egbogi aladun, ti o lagbara ti o si dun yi yio tete mọ ki o gbadun pelu iyanu

**SANTE PASTILLES**

MADE BY ROWNTREES IN ENGLAND


---


## Federal Elections 1959

NO. 187

### USE OF VEHICLES ON POLLING DAY

Candidates and political parties are reminded that no vehicle bearing a party symbol may approach within 200 yards of a polling station (Regulation 114 (5).

No other special restrictions have been placed on the movement of vehicles on polling day either by the Electoral Commission (using their powers under Regulation 1(2) or by Police.

**R. E. WRAITH**
Chairman
Electoral Commission


---


# Iṣẹ yiowu ki o jẹ...
## Mọto MORRIS oni-tọnun meje ti o ntakiti ẹru silẹ yio ru gbogbo ohun-eelo iṣẹ na

Fun awọn ẹru ti o tobi ati iṣẹ ti o nira o yẹ ki o ni nkan ti o to gbẹkẹle, agunisa-owo ati ọkọ ti o lagidi dada—O yẹ ki o ni Moto Morris oni-tọnun meje ti o ntakiti ẹru silẹ Mọto Morris le ṣe iṣẹ na fun ọ werewere ati ni faganfaga pelu, a si tun pada wa fun omiran laisa-are. Bi o ba da asiko lati ru ẹru daadẹ kiakia, ra Mọto Morris onitọnun meje ti o ntakiti ẹru silẹ.



**C·F·A·O**

Ẹka Ile-itaja mọto na wa ni Eko . Apapa . Ibadan . Kano . Jos . Enugu Onitsha . Aba.

# ETO IDIBO APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

DECEMBER 9—DECEMBER 15, 1959.

# Yiyan Asoju si ile Igbimọ titun

**Yiyan awọn aṣoju fun idibo Apapọ Ijọba Naijiria, ti Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Eko pari ni ọjọ kọkanlelogun oṣu November, ti Ipinlẹ Ariwa pari ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu November. Eto yi fi aye idibo olukuluku ilu han.**

| ẸGBẸ OṢELU | AMI | IYE AYE | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | NORTH | WEST | LAGOS | EAST | TOTAL |
| ACTION GROUP (AG) | Ọpẹ | 174 | 62 | 3 | 43 | 282 |
| NATIONAL COUNCIL OF NIGERIA AND CAMEROONS (NCNC) | Akukọ | 14 | 62 | 3 | 73 | 152 |
| NORTHERN PEOPLE'S CONGRESS (NPC) | Ọkọ | 170 | 1 | 1 | – | 172 |
| NORTHERN ELEMENTS PROGRESSIVE UNION (NEPU) | Irawọ Oniga-marun | 149 | – | – | – | 149 |
| DEMOCRATIC PARTY OF NIGERIA AND THE CAMEROONS (DPNC) | Erin | – | – | – | 22 | 22 |
| UNITED MUSLIM PARTY (UMP) | Atupa - amọna | – | – | 1 | – | 1 |
| NATIONAL EMANCIPATION LEAGUE (NEL) | Atupa - Ifalọwọ | – | 14 | – | – | 14 |
| NIGERIAN PEASANT PARTY (NPP) | Aworan Oyinbo | – | – | – | – | – |
| NIGER DELTA CONGRESS (NDC) | Ẹja ni ọna mẹta | – | 3 | – | 5 | 8 |
| (UMBC Independent) | Ọdẹ | 2 | – | – | – | 2 |
| IGALA DIVISIONAL UNION NPC Alliance (IDU) | Kiniun | 4 | – | – | – | 4 |
| IJEBU PARAPO PARTY (IPP) | Kọkọrọ | – | – | – | – | – |
| IGBIRRA TRIBAL UNION (ITU) | Ọfa | 1 | – | – | – | 1 |
| IGBIRRA TRIBAL UNION /NPC Alliance | Asia Alawọmẹta | – | – | – | – | – |
| OSHUN UNITED PARTY (OUP) | Eso-ninu Apẹrẹ | – | 1 | – | – | 1 |
| EGBE OMO IBILE AKURE ATI AGBEGBE (E.O.I) | Agogohihan | – | – | – | – | – |
| INDEPENDENT CANDIDATES | Ami Orişirişi | 57 | 33 | – | 38 | 128 |
| **IYE AṢOJU TI WỌN YAN SODE** | | 571 | 176 | 8 | 181 | 936 |

AWỌN EGBE OSELU NINU ILE IGBIMO ATIJO

IPO AWON EGBE OSELU NINU ILE IGBIMO ATIJO

| | |
|---|---|
| NPC | 78 |
| NCNC | 51 |
| AG | 35 |
| KNC | 6 |
| UNIP | 1 |
| NLCP | 2 |
| INDEPENDENT | 6 |

Alagba Olola Fredrick Metcalfe. Alakoso Alhaji Abubakar Tafawa Balewa (NPC), Alhadji Muhammadu Ribadu, Minista Alamojuto Eto Arin Ilu Eko ati Ohun Isura Ile, Alhadji Muhammadu Inua Wada, Minista Alamojuto Ise Ijoba, Malam Zana Bukar Dipcharima, Minista Alamojuto Ise Owo ati Ise Owo; (NCNC) Ogbeni Joseph Modupe Johnson, Minista Alamojuto Ise ati Alafia Arin Ilu; Oloye Festus Okotie-Eboh, Minista Alamoju Eto Inawo; Ogbeni R. A. Njoku, Alamojuto Eto Ise Igbokegbodo Oko; Ogbeni Aja Nwachuku, Alamojuto Eto Eko; (Action Group) Oloye S. L. Akintola, Minista Alamojuto Eto Ise Waya ati Il Okofurufu; Oloye Ayo Rosiji, Minista Alamojuto Eto Ilera. (KNC) Ogbeni Victor Mukete, Minista Alamojuto Eto Iwadi ati Irohin Ijoba.

Ninu awon asoju merindelogosan (184) na, gbogbo won ni nwon tun dupo pe ki nwon dibo fun awon wo Ile Igbimo pada afi Oloye S. L. Akintola nikan.

Eto ti awon ara Ipinle Ariwa fi dibo fun awon Igbimo Apapo Ijoba Naijiria wole Igbimo Atijo ni Ibo-adi-lon-di (Electoral College) gegbon awon eniti o ba dagba to lati dibo ni o di Ibo ni Ipinle Iwo-Orun, Ila-Orun ati l'Eko.

**Awon adibo ti o ti fi oruko sile lati dibo je.**

| | |
|---|---|
| NORTH | 3,640,284 |
| EAST | 2,592,631 |
| WEST | 2,653,188 |
| LAGOS | 144,377 |
| TOTAL | 9,030,480 |

# GBOGBO AWỌN AṢOJU TI O FẸ DIJE WỌ ILE IGBIMỌ APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA NIYI :-

## Northern Region

ADAMAWA PROVINCE

ADAMAWA

MURI

NUMAN

BAUCHI PROVINCE

BAUCHI

GOMBE

KATAGUM

BENUE PROVINCE

IDOMA

LAFIA

NASARAWA

TIV

WUKARI

BORNU PROVINCE

BEDDE

ILORIN PROVINCE

BORGU

ILORIN

LAFIAGI PATEGI

KABBA PROVINCE

IGALA

IGBIRRA

KADUNA CAPITAL TERRITORY

KANO PROVINCE

KANO

KANO NORTHERN

KATSINA PROVINCE

KATSINA

NIGER PROVINCE

BIDA

KONTAGORA

PLATEAU PROVINCE

AKWANGA

LOWLAND

PANKSHIN

SOKOTO PROVINCE

ARGUNGU

GWANDU

SOKOTO

ZARIA PROVINCE

ZARIA

## Western Region

ABEOKUTA

EGBA

AFENMAI

ASABA




# Ẹ dibo fọpẹ nitori idẹra ati Ominira

**Bi ẹ ba dibo f'Ọpẹ, eto anfani idẹra mẹrinla ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre seleri pe, yio tẹ nyin lọwọ bi awọn ba jagunmolu niwọnyi:—**

### ẸKỌ

(1) Ẹkọ ọlọfẹ fun awọn ọmọde alakọbẹrẹ ati fun awọn ti o nlọ si Ile-Ẹkọ-Giga bi Grammar Schools, Secondary Technical Colleges ati Trade Centres. Alafia ati ominira yio wa fun ẹnikẹni, ko si ni si pe ẹnikan nñ iya jẹ ẹnikan mọ rara yika gbogbo ilẹ Naijiria.

### ETO ILERA

Gbogbo awọn ọmọde, lati ọmọ-ọwọ titi de ọmọ ọdun mejidilogun ti o ba wa ni Ipinlẹ Ariwa ati Ipinlẹ Ila-Orun yio ma a jẹ anfani gbigba ẹgbogi lọfẹ fun iwosan, nwọn yio si kọ awọn ile-iwosan (Hospital) Ile-itọju-Alaisan (Dispensary) ati ile-itọju aboyun at'awọn abiamọ yika gbogbo ilu, paapa julọ ni Ipinlẹ Ariwa ati Ipinlẹ Ila-Orun ati si gbogbo ilu. Larin ọdun kini ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ba di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ni nwọn yio ti ṣe eto bi ẹniti o ba dagba ju ọdun mejidilogun lọ yio ti ṣe ma a gbe ẹgbogi lọfẹ.

### OWO TI O JỌJU FUN AWỌN OṢIṢẸ

(3) Gbogbo awọn oniṣẹ ojumọ ni yio ma a gba ṣile marun (5s.) ojumọ yika gbogbo ilu patapata ki owo wọn le to o na.

### ATUNṢE OWO OṢU ATI OWO OJUMỌ

(4) Eto atunṣe owo oṣu fun gbogbo awọn oṣiṣẹ yio bẹrẹ ki ọjọ gbigba ominira Ijọba to de.

### IṢẸ YIO WA FUN ẸNIKẸNI LATI ṢE

(5) Gbogbo ọmọ Naijiria ni yio ri iṣẹ ṣe, ẹniti ko ba si ti i ri iṣẹ ṣe yio ma a gba owo idapọ-duro titi ti yio fi ri iṣẹ, nitori airiṣẹṣe yi ni o ngmu awọn ọmọ Ipinlẹ Ila-Orun lọ ṣiṣẹ ni Fernado-Po.

### OWO-IFẸHINTI FUN AWỌN OṢIṢẸ OJUMỌ

(6) Nitori ki awọn oṣiṣẹ ojumọ ti nwọn nṣiṣẹ lile fun wakati merinlelogoji lọsẹ, ti owo iṣẹ wọn si kere, ma ba a di alagbe ati atọrọjẹ nigbati nwọn ba darugbo ti nwọn ko le ṣiṣẹ mọ, Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio pese owo-ifẹhinti ti nwọn yio ma a gba titi di ọjọ-iku wọn.

### ATUNṢE AWỌN IGBERIKO

(7) Ipese irinṣẹ titun yio wa fun awọn agbẹ, ẹrọ isọrọ si okere yio wa yika gbogbo ilu, nwọn yio si la ọna Reluwe yika gbogbo ilẹ Naijiria, iranlọwọ Ijọba yio si wa fun awọn Fulani ti o nsin malu ati agutan lati ma a ri ere pupọ jẹ lori ẹran ọsin ati ohun-ọgbin wọn.

### ILE KIKỌ

(8) Gbogbo enia ti ko ni owo pupọ yio ri ile ra lawin lati ma a san owo rẹ diẹdiẹ fun igba pipẹ. Ki o to di ọdun marun ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, gbogbo awọn abule ti o wa ni igberiko ni yio di onile alarabara titun ti o fuyi loju.

### OWO IFẸHINTI FUN AWỌN ARUGBO

(9) Ipese owo-ifẹhinti wa fun awọn arugbo ti ko ngba owo ile tabi ni owo ipamọ lati fi jẹun ati fun isinmi ẹmi wọn, titi di ọjọ iku wọn.

### ITỌJU AWỌN AFỌJU

(10) Ipese Ile-ẹkọṣẹ ati ile-gbigbe yio wa fun gbogbo awọn afọju ati awọn abirun ti ko lagbara bi awọn agewọ ati agesẹ jakejado gbogbo ilẹ Naijiria.

### AWỌN TI O TI JAGUN RI

(11) Ipese owo, okẹ-mẹdọgbọn ponun (£500,000) yio wa fun awọn ti o ti jagun ri, ti a o fi le wọn lọwọ gẹgẹbi owo ilẹlẹ kini pe, ki nwọn lọ fi kọ Ile-iṣẹ fun anfani gbogbo awọn enia ti o ti jagun ri ati lati fi kọ awọn ibugbe ile fun aabo wọn pẹlu.

### IDASILẸ AWỌN ẸYA ILU KEEKEEKE

(12) A o da awọn Ẹya Ilu Keekeeke bi Awọn Ilu Etido (C.O.R. States), Awọn Ilu Arin Iwọ-Orun (Midwest State) ati Awọn Ilu ti o wa ni Aala Agbedemeji Ipinlẹ Ariwa (Middle Belt State) silẹ lati ma a ṣe akoso Ijọba tiwọn funra ara wọn ki o to to ọjọ kini osu kẹwa ọdun 1960. A o si tun pa Ẹkun Ilọrin ati Kabba pọ mọ Ipinlẹ Iwọ-Orun.

### IJỌBA RERE ALANU

(13) Ijọba Rere Alanu ni Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio jẹ bi o ba di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, ominira yio wa fun ẹnikẹni, iwa kannpa ati ki a ma a fi agbara te ẹnikan loriba tabi ki a ma a da awọn enia sẹwọn lainidi ko ni si mọ.

### IDARIJI WA FUN AWỌN TI O TI WẸWỌN NITORI IṢELU

(14) Ni ọjọ ti a ba gba Ominira Apapọ Ijọba Naijiria gangan ni a o da gbogbo awọn ti o wa l'ogba ẹwọn nitori oran Iṣelu silẹ, ti a o si dariji gbogbo awọn ti o ti wẹwọn ri itori Ọran Iṣelu pe, "nwọn ko lọ si ẹwọn ri" lati nu gbogbo ẹgbin ẹwọn na nu kuro lara wọn.

# OWE ILẸ YORUBA

Lati ọwọ Felix Oluwafẹmi Ajayi, Idda-Ajinnare-Ekiti

1. Ohun ti oju afọju ti ri ki oju rẹ to fọ lo ti ri mọ.
2. Ologinni rajo, ile dile ekute.
3. Asọrọ ibajẹ sebi t'on la nwi, aṣe-buburu, ẹ ku ara fu.
4. Aṣiri ikoko, aja kọ ni yio tu u.
5. Atori-ọmọ fẹ ọbun ṣe aya ọbun ọmọ ni yio bi.
6. Ekuru pa adẹtẹ, ki onifo kiyesara.
7. Oju ẹni ba re ajo ki i to ile rẹ lẹhin.
8. Ohun ti a ba fẹran ju lo npa ni, ewo ada lo nka ada lehin.
9. Kini onisọna-awọ gbekalẹ ti o nle ewurẹ nidi rẹ?
10. Iku ti o npa ọdẹ mbẹ ninu apo, eyiti o npa agbẹ mbẹ lọrun ebe, eyiti o npa alangba mbẹ lẹba ogiri.
11. Bi apa agbalagba ko ba ka ọmọde mọ ni o nsọ wipe "afi bi ọmọde yi ba lu on pa nihin loni".
12. Kini ẹgbọ nṣe ti o sọ pe on ko raye wa omi?
13. Aṣa wo igbin kọrọ, ko gbọdọ gbe e.
14. Aparo kan ko ga ju ọkan lọ, afi eyiti o ba gori ebe.
15. Bi a ko ba ni inkanagba, bi ewe la nri.
16. Ori ti yio run agbado sun, lati ọrun ni yio ti gbe agbada waiye.
17. Ire ẹni ki i kọja ori ẹni
18. Wa mi, ki nwa ọ ni ọrẹ fi ndun.
19. Aya ti iwa rẹ ba dara lo ngmu inu ọkọ dun.
20. Adun ni i kẹhin ewuro adun ni yio gbẹhin fun gbogbo wa.



# Ẹ dibo fọpẹ nitori idẹra ati Ominira

**Bi ẹ ba dibo f'Ọpẹ, eto anfani idẹra mẹrinla ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣeleri pe, yio tẹ nyin lọwọ bi awọn ba jagunmolu niwọnyi:—**

### ẸKỌ

(1) Ẹkọ ọlọfẹ fun awọn ọmọde alakọbẹrẹ ati fun awọn ti o nlọ si Ile-Ẹkọ-Giga bi Grammar Schools, Secondary Technical Colleges ati Trade Centres. Alafia ati ominira yio wa fun ẹnikẹni, ko si ni si pe ẹnikan nfi iya jẹ ẹnikan mọ rara yika gbogbo ilẹ Naijiria.

### ETO ILERA

Gbogbo awọn ọmọde, lati ọmọ-ọwọ titi de ọmọ ọdun mejidilogun ti o ba wa ni Ipinlẹ Ariwa ati Ipinlẹ Ila-Orun yio ma a jẹ anfani gbigba egbogi lọfẹ fun iwosan, nwọn yio si kọ awọn ile-iwosan (Hospital) Ile-itọju-Alaisan (Dispensary) ati ile-itọju aboyun at'awọn abiamọ yika gbogbo ilu, paapa julọ ni Ipinlẹ Ariwa ati Ipinlẹ Ila-Orun ati si gbogbo ilu. Larin ọdun kini ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ba di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ni nwọn yio ti ṣe eto bi ẹniti o ba dagba ju ọdun mejidilogun lọ yio ti ṣe ma a gbe egbogi lọfẹ.

### OWO TI O JỌJU FUN AWỌN OṢIṢẸ

(3) Gbogbo awọn oniṣẹ ojumọ ni yio ma a gba ṣile marun (5s.) ojumọ yika gbogbo ilu patapata ki owo wọn le to o na.

### ATUNṢE OWO OṢU ATI OWO OJUMỌ

(4) Eto atunṣe owo oṣu fun gbogbo awọn oṣiṣẹ yio bẹrẹ ki ọjọ gbigba ominira Ijọba to de.

### IṢẸ YIO WA FUN ẸNIKẸNI LATI ṢE

(5) Gbogbo ọmọ Naijiria ni yio ri iṣe ṣe, ẹniti ko ba si ti i ri iṣẹ ṣe yio ma a gba owo idapọ-duro titi ti yio fi ri iṣẹ, nitori airiṣeṣe yi ni o ngmu awọn ọmọ Ipinlẹ Ila-Orun lọ ṣiṣẹ ni Fernado-Po.

### OWO-IFẸHINTI FUN AWỌN OṢIṢẸ OJUMỌ

(6) Nitori ki awọn oṣiṣẹ ojumọ ti nwọn nṣiṣẹ lile fun wakati mẹrinlelogoji lọsẹ, ti owo iṣẹ wọn si kere, ma ba a di alagbe ati atọrọjẹ nigbati nwọn ba darugbo ti nwọn ko le ṣiṣẹ mọ, Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio pese owo-ifẹhinti ti nwọn yio ma a gba titi di ọjọ-iku wọn.

### ATUNṢE AWỌN IGBERIKO

(7) Ipese irinṣẹ titun yio wa fun awọn agbẹ, ẹrọ isọrọ si okere yio wa yika gbogbo ilu, nwọn yio si la ọna Reluwe yika gbogbo ilẹ Naijiria, iranlọwọ Ijọba yio si wa fun awọn Fulani ti o nsin malu ati agutan lati ma a ri ere pupọ jẹ lori ẹran ọsin ati ohun-ọgbin wọn.

### ILE KIKỌ

(8) Gbogbo enia ti ko ni owo pupọ yio ri ile ra lawin lati ma a san owo rẹ diẹdiẹ fun igba pipẹ. Ki o to di ọdun marun ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, gbogbo awọn abule ti o wa ni igberiko ni yio di onile alarabara titun ti o fuyi loju.

### OWO IFẸHINTI FUN AWỌN ARUGBO

(9) Ipese owo-ifẹhinti wa fun awọn arugbo ti ko ngba owo ile tabi ni owo ipamọ lati fi jẹun ati fun isinmi ẹmi wọn, titi di ọjọ iku wọn.

### ITỌJU AWỌN AFỌJU

(10) Ipese ile-ẹkọṣẹ ati ile-gbigbe yio wa fun gbogbo awọn afọju ati awọn abirun ti ko lagbara bi awọn agewọ ati agesẹ jakejado gbogbo ilẹ Naijiria.

### AWỌN TI O TI JAGUN RI

(11) Ipese owo, ọkẹ-mẹdogbọn ponun (£500,000) yio wa fun awọn ti o ti jagun ri, ti a o fi le wọn lọwọ gẹgẹbi owo ilele kini pe, ki nwọn lọ fi kọ Ile-iṣẹ fun anfani gbogbo awọn enia ti o ti jagun ri ati lati fi kọ awọn ibugbe ile fun aabo wọn pẹlu.

### IDASILẸ AWỌN ẸYA ILU KEEKEEKE

(12) A o da awọn Ẹya Ilu Keekeeke bi Awọn Ilu Etido (C.O.R. States), Awọn Ilu Arin Iwọ-Orun (Midwest State) ati Awọn Ilu ti o wa ni Aala Agbedemeji Ipinlẹ Ariwa (Middle Belt State) silẹ lati ma a ṣe akoso Ijọba tiwọn funra ara wọn ki o to to ọjọ kini osu kẹwa ọdun 1960. A o si tun pa Ẹkun Ilorin ati Kabba pọ mọ Ipinlẹ Iwọ-Orun.

### IJỌBA RERE ALANU

(13) Ijọba Rere Alanu ni Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio jẹ bi o ba di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, ominira yio wa fun ẹnikẹni, iwa kannpa ati ki a ma a fi agbara tẹ ẹnikan loriba tabi ki a ma a da awọn enia sẹwọn lainidi ko ni si mọ.

### IDARIJI WA FUN AWỌN TI O TI WẸWỌN NITORI IṢELU

(14) Ni ọjọ ti a ba gba Ominira Apapọ Ijọba Naijiria gangan ni a o da gbogbo awọn ti o wa l'ọgba ẹwọn nitori oran Iṣelu silẹ, ti a o si dariji gbogbo awọn ti o ti wẹwọn ri itori Ọran Iṣelu pe, "nwọn ko lọ si ẹwọn ri" lati nu gbogbo ẹgbin ẹwọn na nu kuro lara won.

# OWE ILẸ YORUBA

Lati ọwọ Felix Oluwafemi Ajayi, Idda-Ajinnare-Ekiti

1. Ohun ti oju afọju ti ri ki oju rẹ to fọ lo ti ri mọ.
2. Ologinni rajo, ile dile ekute.
3. Asọrọ ibajẹ ṣebi t'on la nwi, aṣe-buburu, ẹ ku ara fu.
4. Aṣiri ikoko, aja kọ ni yio tu u.
5. Atori-ọmọ fẹ ọbun ṣe aya ọbun ọmọ ni yio bi.
6. Ekuru pa adẹtẹ, ki onifọ kiyesara.
7. Oju ẹni ba re ajo ki i to ile rẹ lẹhin.
8. Ohun ti a ba fẹran ju lo npa ni, owo ada lo nka ada lẹhin.
9. Kini ' onisọna-awọ gbekalẹ ti o nle ewurẹ nidi rẹ?
10. Iku ti o npa ọdẹ mbẹ ninu apo, eyiti o npa agbẹ mbẹ lọrun ebe, eyiti o npa alangba mbẹ lẹba ogiri.
11. Bi apa agbalagba ko ba ka ọmọde mọ ni o nsọ wipe "afi bi ọmọde yi ba lu on pa nihin loni".
12. Kini egbọ nṣe ti o sọ pe on ko raye wa omi?
13. Aṣa wo igbin kọrọ, ko gbọdọ gbe e.
14. Aparo kan ko ga ju ọkan lọ, afi eyiti o ba gori ebe.
15. Bi a ko ba ni inkan-agba, bi ewe la nri.
16. Ori ti yio run agbado sun, lati ọrun ni yio ti gbe agbada waiye.
17. Ire ẹni ki i kọja ori ẹni
18. Wa mi, ki nwa ọ ni ọrẹ fi ndun.
19. Aya ti iwa rẹ ba dara lo ngmu inu ọkọ dun.
20. Adun ni i kẹhin ewuro adun ni yio gbẹhin fun gbogbo wa.




# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Awolọwọ ni : Awọn Alamojuto ni awọn ran lọ silẹ Hausa

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o kọja yi ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe ikede lati fi ja'rọ ẹsun-eke ti awọn Ẹgbẹ Alakukọ ati Egbẹ Olomi fi nla atagba larin ara won pe awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ẹgbaa janduku ranṣẹ si Ipinlẹ Ariwa lati fi da ilu ru.

Oloye Awolọwo ni irọ gba a ni ọrọ-agbọsọ yi, ẹsun-eke si ni pẹlu. Nitori awọn ẹgbaa enia ti awọn ran lọ si Ipinlẹ Ariwa, awọn ran wọn lọ ṣe alamojuto ati ẹlẹri fun awọn aṣoju ti awọn yan s'ode lati dibo fun ni Ipinlẹ Ariwa ni.

Awolọwọ si tun se alaye pe bi o ba ṣepe janduku ni wọn ni awọn kọ ni fi orukọ won ati gbogbo irinsi wọn ṣọwọ si Gomina-agba ati si i Olori awọn Ọga-ọlọpa (Inspector-General) gẹgẹbi awọn ti ṣe ki awọn enia na to bẹrẹ irin-ajo wọn si Ipinlẹ Ariwa.

## Oloye Kọsọkọ se aseidagbere fun ọmọ rẹ

EKO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kọkanla ọdun yi ni Ọmọ-ọba Oloye Aminu Kosọkọ, Asajon Ọlọja Ereko se ase idagbere fun ọmọbirin rẹ, Ọmọ-ọba Ganiyat Adewunmi. Kosokọ ni iga rẹ: fun ilu Oyinbọ ti ọmọ na lọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kini oṣu yi lati lọ kọ ẹkọ.

Ẹsẹ awọn enia pataki pataki ni o pe ṣọṣọ si ibi aṣeyẹ na, Oloye na si fi orişirişi onjẹ adidun ati orişirişi ọti tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun lati arọ titi agogo mẹwa alẹ. Olori Oloye na Ọmọ-ọba Shadiya ṣe gudugudu meje lọjọ na, onjẹ ti o se gbadun pupọ. Irohin ko to afojuba ni aṣeyẹ ọjọ na, o buaiya o le gongo.

Alọ a dara, abọ a sunwọn o.

## Ẹniti o yinbọn ṣẹyẹ fun Ẹgbẹ Alakukọ ṣe ara rẹ leṣe

ABA.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu ti o koja yi nigbati Ọgbẹni James Mark yinbọn lati fi ṣe ẹyẹ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti Oloye M. W. Ubani ko lọ si Ihie-Ukwu ni Ekun Aba fun ikede idibo ni ibọn na ba ṣeeşi re ba a, o si pa a lara pupọ. Nwọn si ti gbe e lọ si Ile-iwosan fun itọju, irohin ti o jade lati ile iwosan ni pe ninu bi yio ku-bi yio ye ni o wa.

# Obirin kan bi ewele ọmọ ni Kaduna

KADUNA.

NI alẹ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o kọja yi ni obirin kan bi ewele kan si ile awọn abiyamọ ni Ile-iwosan Ijọba Ewele na ni imu ti o tẹ perẹsẹ ati oju kan ni iwaju ori rẹ, o si ku ki o to to arọ ọjọ keji ti nwọn bi i.

Ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn gburo pe nwọn bi ewele na ni o yalẹnu, nwọn si nrọ wa wo o ni Ile-iwosan na, ṣugbọn nwọn ko jẹki nwọn ri i. Awọn ti o nṣiṣẹ ninu Ile-iwosan na sọ wipe, eyi ni akọkọ ti nwọn bi irufẹ rẹ sibẹ.

## Ẹniti ona owo-aiyederu wẹwọn oṣu mejila

KANO.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni Adajọ Kotu kan ni Kano sọ ọdaran kan Anthony Umoren, ẹni ọdun mejidinlọgbon ti nṣiṣẹ gbakeji akọwe ni ṣọbu oni-lẹtiriki si ẹwọn oṣu mejila: nitori ti o jẹbi ẹsun owo aiyederu.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun ni pe, ni ọjọ kejila oṣu ti o kọja yi ni o lọ da pọnun kọọkan mẹta owo aiyederu pọ mọ owo san fun akọwe-owo ile Banki ki nwọn to mu u.


MULTIVITE

KORO EGBOGI-IMARALE

fun awọn ọmọge . .



Awọn ọdọmọbirin ni lati ma a lo MULTIVITE nitoripe o ni ẹgbogi-imarale "c" ti o nran awọ-ara lọwọ lati mọ gara ki o si jolo, o si njẹki ehin fidimulẹ ki o si lagbara.

Koro MULTIVITE NI:

Egbogi-imarale "A": ti o nran enia lọwọ lati le farada awọn aisan bi otutu-iba ati ayọkẹlẹ.

Egbogi-imarale "B": ti o nran enia lọwọ lati ṣegun aarẹ inu-ọpọlọ.

Egbogi-imarale "D": jẹ pataki pupọ fun awọn aboyun nitoripe o nṣe iranlọwọ lati jẹki egungun awọn ọmọ-tuntun to si ọkankan ki o si lagbara.




THE BRITISH DRUG HOUSES LTD. LONDON

Distributed by branches of THE UNITED AFRICA CO. OF NIGERIA LTD.



Iwọ yio ri i pe ẹwu-iṣẹ re l'ọmọ ju OMO lofi fo o.



Wo iyatọ ti o wa ninu ẹwu-iṣẹ mejeji yi—bẹ e nwọn ṣeṣẹ fọ awọn mejeji tan ni! Eyi ti nwọn fi OMO fọ ni o mọ garaga ti o si tan ju. Gbogbo awọn aṣọ rẹ alawọ orisirisi ati funfun ni yio si mọ ti yio si ṣe garaga nigbati o ba fi OMO fọ wọn.




OMO ni o nfọ AṢỌ MỌ JULỌ ni gbogbo aiye!

# GBOGBO AWỌN AṢOJU TI O FẸ DIJE WỌ ILE IGBIMỌ APAPỌ IJỌBA NAIJIRIA

Lati oju ewe kejila

## EKET

264. EKET EAST
Okon J. Emirue (AG)
Dr. Esin A Esin (NCNC)

265. EKET WEST
Timothy I. E. Udo (AG)
★ James L. Nsima (NCNC)
Daniel J. Edohe (Ind.)

## ENYONG

266. ENYONG NORTH
Isaac Ahl (AG)
Johnson U. Udenyi (NCNC)
Timothy Utchay (Ind.)

267. ENYONG SOUTH
Patrick Ekanem (AG)
Edet Akpan Udo (NCNC)
A. U. Ekanem (Ind.)

## IKOM

268. IKOM
F. Akonjom (AG)
P. Ejukwa (NCNC

## IKOT EKPENE

269. IKOT-EKPENE CENTRAL
Bassey Ukpong (A.G.)
★ Henry Akpan Udo (NCNC).

270 IKOT EKPENE NORTH
Samson Udo Idiong (AG)
Bassey Obot Nya (Ind.)
Okon William Inyang (NCNC)

271. IKOT EKPENE SOUTH
Munchin Ben Afanideh (AG)
Akpan Ekuninam Bassey (NCNC)

## NSUKKA

272. NSUKKA CENTRAL
Sylvanus Eze (AG)
Sylvester U. Alunwana (Ind.)
Francis A M. Amadi (NCNC)

273. NSUKKA NORTH
Garuba Gusau (AG)
★ Daniel Chukwuma Ugwu (NCNC)

274. NSUKKA EAST
Joseph Alumona Nwamba (AG)
Samuel Namani Nwaroh (Ind.)
★ Nelson Nnadi Onugu (NCNC)

275. NSUKKA WEST
Peter N. Udemezue (DPNC)
Vincent A. Nwalleji (NCNC)

## OBUBRA

276. OBUBRA
Okoi Arikpo (AG)
Ude Ukpabi Eko (NCNC)

## OGOJA

277. OGOJA EAST
Josephat Okpe Ekunke (AG)
John Akpan Odey (NCNC)

278. OGOJA WEST
Michael Akpa Odibu (AG)
Matthew T. Mbu (NCNC)
James B. Ekpong (Ind.)

## OGONI

279. OGONI EAST
N. G. J. Alabi (AG)
★ F. Nwika (NCNC).
F. M. A. Saronwujo (NDC-NPC)

280. OGONI WEST
Monse (AG)
Kemte Gladom (NCNC)
P. B. Poromon (NDC-NPC)
N. Chinwe (Ind.)

## OKIGWI

281. OKIGWI CENTRAL
Louis N. Obioha (DPNC)
★ Felix Elendu Offor (NCNC)
Nnegbu Ibeagi (Ind.)

282. OKIGWI NORTH EAST
Michael O. Udeagu (DPNC)
Felix Umelo Ihe (NCNC)
Wellington Ume (Ind.)

283. OKIGWI SOUTH EAST
Alphonsus Ihemeson (AG)
★ Paul Eleke (NCNC).
George Anukwuem (Ind.)

284. OKIGWI SOUTH WEST
Boniface Chide Agu (AG)
Dennis Ahamefula (NCNC)
Sampson Duru Ajero (IND)

## ONITSHA

285. ONITSHA URBAN
Dr. J. E. Iweka (DPNC)
Dr. Nnamdi Azikiwe (NCNC)

286. ONITSHA NORTH CENTRAL
★ Dr. E. O. Awduche (AG)
Dr. P. U. Okeke (NCNC)
Christopher Uzodinma (IND)

287. ONITSHA SOUTH CENTRAL
Kalu Orizu (DPNC)
Mbazulike Amechi (NCNC)

288. ONITSHA NORTH
L. N. Ezeani (NCNC)
Mofunaya Ifemenam (IND)

289. ONITSHA SOUTH
Emeanu Agajiofo (DPNC)
Vincent Ikeotuonye (NCNC)
Mathias Nwogu (IND).

## OPOBO

290. OPOBO NORTH
D. B. Udo Inyang (AG)
I. I. Akpabio (NCNC)

291. OPOBO SOUTH
★ Dr. E. Udoma (AG)
U. O. Ekenokor (NCNC)

## ORLU

292. ORLU NORTH
Titus Egbuefi Egomolo (DPNC)
Egene Onyemusi Ifezue (NCNC)

293. ORLU NORTH EAST
Dr. Kingsley Mbadiwe (DPNC)
Victor Egbogu Eze (NCNC)

294. ORLU SOUTH EAST
Fidelis Edika Nnabuife (DPNC)
Margaret Rose Nwogu (IND)
★ Emmanuel Akwiwu (NCNC).

295. ORLU WEST
Thomas Ihekagbo Uba (DPNC)
Dr. Ben Uzoukwu Nzeribe (NCNC)

## OWERRI

296. OWERRI CENTRAL
Bernand Mbamara (AG)
★ R. A. Njoku (NCNC)
Dr. Eze Oguerl (IND)
Dr. Chiaka Anozi (IND)

297. OWERRI NORTH
Sampson Egbuchilam (AG)
A. U. D. Mba (NCNC)
O. U. Eronini (IND)

298. OWERRI NORTH EAST
H. Ajuzlogu (DPNC)
Adolphous Mba (NCNC)

299 OWERRI EAST
A. Onuoha (AG)
★ D. Abii (NCNC).

300. OWERRI SOUTH EAST
Sam Opara (AG)
Basil Ukaegbu (NCNC)

301. OWERRI WEST
Raphael Okafor (NCNC)
(unopposed)

## PORT HARCOURT

302. PORT HARCOURT
Miss Rachael Brown (AG)
★ Donatus Okay (NCNC)

## UDI

303. ABAJA AND NGWO
★ Gabriel Eneh (NCNC).
Peter U. Nnamani (IND)

304. ENUGU
J. C. A. Onwumilike (DPNC)
C. O. Chiedozie (NCNC)

305. UDI CENTRAL
Ignatius Chikelu (NCNC)
B. N. Nechi (IND)
Jachike M. Okafor (IND)
S. E. Okofor (IND)

306. UDI EAST
Anyi C. Orji (DPNC)
Samuel Nnaji (NCNC)

## UYO

307. UYO NORTH
Sebastian J. Umoren (AG)
Etim Nyong (NCNC

308. UYO SOUTH EAST
P. O. Akpan (AG)
K. I. Etuk (NCNC)

309. UYO SOUTH WEST
Inyang A. Brown (AG)
George T. Etudor (NCNC)
Effiong T. Ekwere (IND)

## SOUHTERN CAMEROONS

Bamenda

Elections postponed in all the 8 constituencies—310—317

## LAGOS

318. LAGOS CENTRAL
★ L. J. Dosunmu (AG)
Chief Fagbenro-Beyioku (NCNC)
M. R. B. Otun (UMP)
O. Yaya (NPC)

319. LAGOS NORTH
A. Onitiri (AG)
★ T. O. S. Benson (NCNC)

320. LAGOS SOUTH
Dr. Oni Akerele (AG)
★ J. M. Johnson (NCNC)





Aworan yi ni apakan awọn ogunlọgọ enia ti o wa si ipade ipolowo idibo ti Oloye Awolọwọ ṣe ni ilu Potiskum· Awọn agbarijọ enia ti o wa ni ilu yi ni awọn Balewa, Hausa, Yoruba, Ibo, Fulani, ati Kare-Kare, gbogbgo wọn ni nwọn si wa gbọ ọrọ Awolọwọ ni ipade na

**Ẹ dibo F'Ọpẹ**

Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 8/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial) and Advertisement Office) Telphone 23675, 23676 Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan. Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.) Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13/-) Olotu S. M. Ademoyiwa. 9 Chapel Street, Lagos.